Lakaye Oro

Aiye ko duro sibi kan, nitoripe a i y e ko loru, Babalawo a ku dandan, Onisegun a ku tefe tefe, Adahnnse ko ni ju sile aiye, bi ilẹ ba ngbe oṣika, ti ko si gbe olotọ, ẹ o ri pe bo pẹ titi ore a su ni ni ṣiṣe.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ "DE" OKUNKUN PARADA.

**Wanted**
TO BUY
VACANT LAND
ANY WHERE IN
LAGOS 200 X 200
Call Personally:-
CROWNSON
16, Bamgboṣe Street
Lagos.

VOL. V No. 317 MONDAY FEBRUARY 19 — FEBRUARY 25 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# ỌDUNRUN OBINRIN TI IPADE DE ỌGBA ITIMỌ-LE NILU EKO

Eko:- Ni ojo alamisi ni awon obinrin Eko ko ara nwon jo, ti nwon si to lo si ile Gomina Agba, Olola Nnamdi Asikiwe. Nwon fe lati lo fi han Gomina pe, awon lodi si owo ori isan.

Awọn Obinrin na le ni igba, ninu wọn arugbo wa, abiyamọ wa, bẹni Wundia si wa. Ṣugbọn akara di egun mọ nwọn lọwọ, nwọn ti Ipade de Ọgba Itimọle.



Awọn Obinrin Ọja na ni a nwo ninu a w o r a n yi nigbati awọn Ọlọpa nko uwọn wọ inu mọto lati lọ ti wọn mọ inu ile Itimọle l'Eko.

Ohun ti o fa eyi ni pe Ijọba Apapọ ti ṣe ofin kan ni oṣu to kọja pe, ẹnikẹni ko gbọdọ ko ara wọn jọ, ki n w ọ n si to ni ọwọ-ọwọ ka ilu Eko, Ofin yi yio ṣiṣẹ fun o ṣ u kan. Ofin yi ni awọn Obinrin Eko lu, ti Ọlọpa si mu wọn.

Ni ọjọ Alamisi Ọlọpa ko nwọn lọ siwaju Adajọ, nwọn si ro ẹjọ pe a w ọ n ko jẹbi. Ṣugbọn Adajọ ko iti da ẹjọ nwọn. Loni ni wọn gbe ẹjọ nwọn na si.

Ki Oluwa ma jẹ ki eyi ti a ko ro ba eyi ti a ro jẹ o.

## Adajo da Ewon Adorun Odun

IJẸBU ODE:- Ninu Kọtu Asaisi ti nwọn ṣe nigboro ilu Ijẹbu Ode, ninu eyiti Ijọba mba awọn gbajumọ mẹtala kan ṣe ẹjọ Ọlọṣa, Ole ati Fọle-fọle, Adajọ da awọn enia na lẹbi, o ni ki awọn enia na lọ si ẹwọn adọrun ọdun papọ, ki a si na gbogbo wọn papọ ni ọgọta bulala.

Ṣeranwo gbe boroki nigbati awọn Ọlọpa ni ki awọn Ọlọṣa mẹtala na wọ mọto Black Mariya, nwọn taku wọnle pe rara, awọn ko ni wọ mọto, ọrọ na si di ogun fanfa.

Awọn Ọlọpa ti gbọ pe, awọn enia na mu Ibọn ati Ada dani, nwọn lọ fi fọ ile kan ni Abule Ararọmi.

Nwọn ri Aṣọ ati G o l u gba pada eyiti owo rẹ to, ẹdẹgbẹrun pọun lọwọ wọn, gẹgẹ bi awọn Ọlọpa ti mura wọn silẹ tẹlẹ nwọn mbẹ lọgba ẹwọn nisisiyi.

**TO LEASE**

SELF CONTAINED HOUSE 12, ROOMS IN LAGOS £400 per Annum

Apply to:—

**Crownson Odujobi**

1st Floor 16, Bamgboṣe Street, Lagos.

# ỌRỌ OLOTU

## E ge Owo ti nyin na ku

Gẹgẹbi eto iṣọ owo na ti gbogbo Ijọba Naijiria ti pinnu lati ṣe, Ijọba Ila Orun pinnu lati din aye ọfẹ ti nwọn nfun Oṣiṣẹ wọn ku, isimi ọfẹ nigbati ara enia ko ba da t a b i nigbati obinrin ba bimọ yio si ma wa larin ọjọ ti a o ka gẹgẹbi ọjọ isimi ti o tọ si Oṣiṣẹ kọkan lọdọdun.

Ni totọ eyi yio din inawo Ijọba ku, ṣugbọn njẹ ni hin ni o ha yẹ ki Ijọba Ila Orun duro? Kini ṣe ti nwọn ko le ge owo oṣu ti wọn ku? Kini ṣe ti nwọn ko da owo epo ọfẹ fun mọto Oṣelu duro? Ki ni ṣe ti wọn ko le ma gba owo ile lọwọ awọn Oṣiṣẹ ti o ngbe ile Ijọba lọfẹ, papa nigbati awọn ti o ngbe ibẹ jẹ enia nla-nla, ti nwọn ngba bi apo mẹjọ si mẹwa tabi ju bẹ lọ lọdun?

Eto ti Ijọba Ila Orun gbe yọ yi ti nlọ ni Iwọ O r u n le lọdun, nitorina ko ṣe ajeji si wa, o tilẹ ya ni lẹnu pe Ila-Orun ṣẹṣẹ ṣe iru eyi ni.

Ohun ti o tun ya ni lẹnu ni wipe bi ẹgbẹ NCNC ti ki gbe to ni ipade ti nwọn ṣe pe, awọn yio ge owo Oṣelu ku, Ijọba Ila-Orun ni biti nwọn ti nṣe Ijọba ko ge owo na lati ọjọ yi. Lẹhin ikede wọn, ni Iwọ-Orun ge owo ti wọn ati owo awọn Oṣiṣẹ ti o ngbowo nla-nla ṣugbọn kaka ki Ila Orun ṣe eyi, mẹkunnu ni o doju kọ.

Ẹ ge owo ti yin na ku, ẹ da owo epo ọfẹ fun mọto duro, ẹ mu ileri ti ẹ ṣe nipade yin ṣẹ. Nigbana ni a o mọ wipe ẹni ifẹ Naijiria ju ti ara yin lọ.

## Olympio nki Olubadan



Nigbati Olori awọn O ṣ e l u (President) ilẹ Togoland fi wa bẹ ilẹ Naijiria wo, ni akoko ti awọn e n i a nlanla Orilẹ aiye fi wa bẹ ilẹ Naijiria wo, ni ọkunrin ti a nwo ni ọwọ osi yi ti orukọ rẹ njẹ Olympio ara ilu Togoland wa pẹlu wọn, o si mbẹ ninu awọn alejo ti o lọ bẹ ilu Ibadan wo. On na ni a nwo n i n u aworan yi nigbati on nki Ọba I. B. A k i n y ẹ l e, Ọ b a ilu I b a d a nlo kẹhin si wa ninu aworan yi.

## Onisegun kan jewo wipe, agbari Oba ni on fi gun ose Awure

OKE-ỌDAN:- A gbọ irohin wipe Ọkunrin Oniṣegun kan ara ilẹ Dahọmi ti orukọ rẹ njẹ Gbetọsọ ni awọn Ọlọpa lọ kamọ inu ile rẹ ti wọn si ki mọlẹ, ninu awọn egbogi ti wọn ri ko ninu ile Oniṣegun na ni agbari enia meji, ọṣẹ wa ninu ọkan, ekeji jẹ ofifo. Nigbati awọn Ọlọpa bere lọwọ, oniṣegun na wipe iṣẹ kini ọṣẹ na nse? o dahun wipe ori odidi ọba kan ni on fi ṣe ọṣẹ awure na.

# IWE SI OLOTU

## Itan Sebotimo dun pupo

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye lati bẹ arabinrin wa Funmilayọ Kofoworọla ti o nkọ itan Sebotimọ, Jọwọ arabinrin wa, a bẹ ọ, Itan yin dara, yio si dun mọ wa ninu pupọ bi o ba nkọ itan na dede fun anfani gbogbo awọn Onkawe Irohin Imọlẹ, nitori itan na ma nkun fun ọgbọn pẹlu lakaye.

A nlẹ Itan yin dede ni ọsọsẹ

Emi ni:-

OKITIPUPA TIMOTHY LIJỌKA

## O seun, Oloye S. L. Akintola

Mba ṣọpẹ bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le gba mi laiye lati ki Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun S. L. A. ku orire, nipa owo awọn Alaṣẹ ati awọn Oṣiṣẹ Ijọba rẹ ti o din ku. O jẹ ohun ti o dun mọ gbogbo enia Ipinle Iwọ - Orun ninu Itan nla lo si tun jẹ fun gbogbo enia Ilẹ Naijiria nitori pe eyi ni akọkọ ti a o ge owo awọn Alaṣẹ ku ti o si mu inu gbogbo enia dun O ṣeun, ṣeun Oloye S. L. Akintọla. Iwaju lọ pa Ẹbiti nresi, iwaju ni o ma lọ

Emi ni

IGBO-ỌRA L. A. AKINTUNDE

## Munisipa E ba wa fikun Oko ero (Bosi) ti o nlo si Oshodi fun anfani awon osise

*Ololu/* Jọwọ ba mi sọrọ ẹdun ọkan mi yi jade fun awọn Munisipa, nitoripe ile gbigbe di Golu larin ilu Eko ati ri ile Haya di ijọgbọn ni Igboro ilu Ebute-Mẹtta Yaba ni ki lo ṣubu tẹ on gbogbo awọn Oṣiṣẹ nko lọ ṣatipo ni Oṣhodi di ita Tinubu ki nwọn to ri Mọto wọ, sibẹ sibẹ nwọn nwa sibi iṣẹ nitori onjẹ ọjọ wọn.

Nitori idi eyi mo bẹ ẹnyin Igbimọ Munisipa pe ki ẹ j ọ w ọ bawa fikun awọn Mọto Akero ti o wa nisisiyi ki wọn si le pọ sii ki ẹ si tun ba wa ṣe asepe ki ẹ fun awọn oṣiṣẹ ni anfani Mọto ti o nlọ tara ti ko si ni duro loju ọna nitori pupọ ninu awọn oṣiṣẹ wọnyi lo nṣiṣẹ lọna jinjin rere, omiran nṣiṣẹ ni Okun tabi ni Ikoyi ti o si nilati wọsẹ ni agogo mẹjọ owurọ, irufẹ enia b a y i yio ti ji jade ni ile rẹ lati agogo marun abọ owurọ ko si ni ri mọto wọ titi agogo meje yio fi kọja iṣẹju mẹdogun ṣugbọn ti o ba jẹ pe awọn m ọ t o wọnyi pọ ni idaduro ko ni si to nẹ. Ni idakeji ẹwẹ ti awọn mọto yi ko ba ti si nilẹ to ẹ le fi kun yio jẹ itunu awọn enia wipe ki ẹ ra awọn Kiakia Bọsi diẹ kun awọn Bọsi wọnyi tabi ki ẹ tubọ fi kun Bọlẹkaja ti o wa nisisiyi. Ninu gbogbo imọran mi mo fẹ ki ẹnyin Oṣelu fi eyi si ero nitoripe ni nkan bi oṣu meji tabi mẹta si, awọn ti ko le san owo pupọ fun ile Ijọba yio fi silẹ nwọn yio siwa ibiti nwọn yio ri ile ti owo rẹ ko ga gbe bawo ni wọn yio ma tiṣe de ibiṣẹ. Ẹ jọwọ ẹ ba wa fi kun Bọsi ti o nlọ si Oṣhodi.

Emi ni

JENET OṢHODI

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## ITAN ORO ADANU

LATI ỌWỌ:— JULIUS ADEBAYỌ FADUJI
NO. 301, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Ni ọjọ kan, bi ọkunrin agbẹ kan ti nlọ si oko rẹ n i arọ kutukutu o ri Ikun kan ti njẹ loju ọna, bi okunrin yi ti sun mọ Ikun na ni o mba ara rẹ sọ wipe, ọwọ iba tẹ Ikun yi, nkan iba ṣe ẹnu re loni, Ha! Ikun lo to bayi! O ri bi o ti nyi lọ loju ọna bi odu Ọya. Inu ọkunrin yi dun nigbati I k u n yi nrin lọ loju ọna, ti ko si ko sinu igbẹ, nigbati o ku diẹ ti ọkunrin yi yio fi de ọdọ Ikun, alala yi ko sinu oko kan ti a sẹsẹ da silẹ lẹba ọna ni ọkunrin yi ba fa ada rẹ yọ n i n u akọ, ti o gbe ko ejika rẹ gba o fi ya Ikun na, o le Ikun yi soke o le sodo, ṣugbọn ọwọ rẹ ko tẹ ẹ, o rẹ Ikun, o si rẹ Ọkunrin na papa, I k u n na ko duro, Ọkunrin yi ko si sọ ireti nu rara. Gbogbo ọgbọn alumọkọrọyi ti Ikun mọ ni o lo, ṣugbọn Ọkunrin yi ko pada lẹhin rẹ, nigbati o ku sata ti Ikun yi fi wọ igbẹ, Ọkunrin yio sọ ada si i ṣugbọn ada ko ba Ikun na.

Nibiti Ọkunrin yi gbe ndaniyan lati ki I k u n yi mọlẹ, ko le duro lati mu ada rẹ mọ, nigbati o ku diẹ ki ọwọ a g b ẹ tẹ iru Ikun na, Ikun ko sinu igbẹ, Ọkuurin agbẹ yi ti o ti ṣe wahala pupọ lori Ikun yi lati fi pa rọlu igbẹ tẹle Ikun na Eni igbẹ mu ki gbogbo asọ Ọkunrin yi tutu bi ẹniti o ṣẹ ja sinu odo ni arọ kutukutu, fila rẹ sọnu, gbogbo ẹwu rẹ si faya, lori gbogbo wahala wọnyi Ikun sa wọ igbẹ lọ Ikun lo Ọkunrin yi wahọ, ara kunkun, o pada wa sinu igboro ẹba ọna lati wa ada rẹ, bi ẹbiti ko ba pa eku, yio sa fi ẹyin fẹlẹ hin, o wa ada yi soke, o wa sodo, kori, bẹni Ọkunrin yi ko ni ada meji, ada kanna ni o fi nsan igbo. ti o si fi npa ajuba, ọkanna ni ake ati ọkọ fun nigbati Ọkunrin yi wa ada rẹ titi. ti ko si ri ada yi mọ, o pada lọ si ile pẹlu ibanujẹ.

Bi o ti nlọ si ile p ẹ l u oju fifaro, ni awọn Ọkunrin ti nlọ soko idasan ati awọn obinrin ti nlọ si odo mbi i lere pe, Ọgbẹni eti ri ti gbogbo asọ yin fi ya bayi? Ọkunrin yi bẹrẹ si dahun pe, Ikun lọ ada nu, bi o ti tun rin siwaju si ni ẹlomiran tun bi pe, Ọgbẹni ka si nkan ti oju yin fi faro bayi? Ọkunrin yi dahun pe Ikun lọ, ada sọnu, bi o ti nyọ si ilu ni awọn ti o mọ dada bi lere pe, Eṣe ti o fi tete de bọ loni? o bẹrẹ si da wọn lohun lọ kọ kan pẹlu ibanujẹ pe Adanu, Adanu, lati igba na ni bi e n i a ba ṣe wahala lori nkan ti ko ba jere lori rẹ, awọn enia a ma wipe ada nu adanu bi ẹnikan ba ko wo lọ ra ọja ti o ba si ta ọja na, ti ko ba pe oju owo on papa a sọ fun awọn aladugbo rẹ pẹlu ibanujẹ pe, Mo sowo, mo padanu,

Mo dupẹ lọwọ Olotu ati gbogbo awọn Osisẹ Irohin Imọlẹ pe, ẹ kuṣẹ o. Iwaju ni ọ p a ẹbiti nre si, iwaju ni gbogbo wa yio ma lọ o. O digba.

---

## Kini ohun ti o mo nipa ile Afirika?

1. Tani Olotu titun fun ilẹ Tanganyika?
2. Darukọ Olotu ilu na tẹlẹ ri lẹhin ti wọn gba Ominira lọdun tokọja ki o to fi aye rẹ na silẹ.
3. Tani Olotu ilẹ Federation of Rhodesia?
4. Tani Alaṣẹ awọn Adajọ ilẹ Ghana?
5. Tani Alaṣẹ Okere fun Ilẹ Ghana?
6. Ọdun wo ni wọn ṣi ọkọ oju Irin lati Eko lọ si ilu Ibadan?
7. Ọdun wo ni a bi Oloye Festus Okotiẹ Eboh?
8. Darukọ Odo ti o gun julọ ni gbogbo aiye?
9. Tani Olori Ẹgbẹ Kenya Afirika National Union?
10. Ilu bo ni a bi si?

WO IDAHUN AWỌN IBERE WỌNYI NI OJU EWE KEJE

---

## Obinrin ara Ile Uganda to koko sise X Rays



Ọmọ binrin ti a nwo yi, ti o r u k ọ rẹ njẹ Margaret Sanyi, ọmọ ọdun mọkanlelogun, on ni a gbọ w i p e ori rẹ ya si ẹkọ nwọn si fun ni ẹbun ẹkọ ọlọfẹ lọ si ilu Oyinbo lati lọ bi a ti ṣe nfi ẹrọ ya awọn ohun gbogbo ti o mbẹ ninu tifun tẹdọ enia.

Margaret jẹ ẹya Buwalasi, ni apa iha Oke Bugisu nilẹ Uganda, Adọrinlorugba ẹkọ ni yio kọ nipa gẹgẹbi agbari enia ti ri, Bi o ba pari ẹkọ rẹ, yio ma fi ṣe awọn ara ilu rẹ lore,

---

## Idahun Idanwo fun Omo Egbe nipa ere Ikini ni ile Yoruba

Inu mi dun pupọ pe gbogbo ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye lo fẹrẹ dahun awọn ibere nipa Ikini ni ilẹ Yoruba bi o tilẹ jẹ pe diẹ ninu wọn lo gba awọn ibere na, ṣugbọn kosi aye lati darukọ awọn ti o dahun ibere na, nitorina ni a ṣe dahun awọn ibere nikan si isalẹ fun anfani awọn ti ko gba.

EYI NI IDAHUN AWỌN IDANWO NA:-

1. Bi o ba ri Alagbẹdẹ kan, Iwọ yio ki bayi pe, Agbẹdẹ Ogun, arọye o! yio si fe si pe iwọ ye o.
2. Bi o ba ri ẹnikan ti o nkọpẹ. iwọ yio ki ba yi pe, Akoko o! On a si dahun pe Sọgijẹ o.
3. Bi o ba ri obinrin ti ndaro, iwọ yio ki bayi pe, arẹdu o! On a si dahun pe Iyamọpo a gbe ọ.
4. Bi o ba ri Onidiri ti ndirun fun wọn, iwọ yio ki pe, Ojugboro! On na yio dahun wipe Oriya.
5. Bi o ba ri Onisango kan, iwọ yio ki bayi pe, Ọbakoso, yio si dahun pe Oku temi.

# SE BOTIMO APA 7

LATI ỌWỌ:- FUNMILAYỌ KOFOWORỌLA

Gbogbo ẹnyin oluka itan mi ni mo ki jakejado Naijiria pe, ẹku ajabọ ọdun, ọdun na yi, ayabo fun gbogbo wa o lagbara Oluwa, a ko ni tawo na, a ko ni taraka, abimọ lemọ ni ti ẹda Awọn baba wa ni ma powe bayi pe: Ina ọmọ Oluyẹbẹ, Orun ọmọ oluyẹbẹ, Ojo ki rọ ko pa ina idi odidẹrẹ, ọmọ a r a i y e ko ni ri yin gbe ṣe o, lagbara Oduduwa. awọn kanna ni o tun ma wi bayi pe: "Bi a ba mba Ikan wi, a ma mọ ile kun ile. bi a ba mba ṣẹrẹ wi, a ma yọ ọfa kun ọfa. bi a ba mpa opo oṣe ara ni fi san, on lo difa fun Ọrunmila lọjọ kini, nigbati o nṣawo lọ sile Ifẹ, nigbati Ọrunmila de ile Ifẹ o la o lu, o ya lwọfa lọ rẹpẹtẹ, ko tọjọ ko toṣu awọn ọmọ araiye bẹrẹ si ditẹ mọ, laipẹ ojọ o ṣẹgun gbogbo wọn, Odumare a jẹ ki a ṣ ẹ g u n awọn ọta wa o. Amin. Aṣẹ.

Nini-owo ati obinrin ti Ọba fa le lọwọ jijọ lọ si ile, nigbati w ọ n de ile, obinrin na fun lo njẹ, nigbati o jẹun yo tan, o bomi si baluwẹ fun u, o si wẹ, o wa pe obinrin na pe ki o wa fi yara ti on yio sun han on, obinrin na si dalohun pe ki o farabalẹ on n ṣ e eto ibusun ti awọn yio fi jijọ sun lọwọ.

ORI NINI-OWO YI, NIGBATI O GBỌ BAYI

Inu Nini-owo ti dun de ibara idi nigbati o gbọ ọrọ ẹnu obinrin yi, o ni ha! a ṣe ngo tilẹ tun de Ọrun kekere bọ lalẹ yi? Oluwa mo dupẹ bi o ti nro ọrọ vi l ọ w ọ ti inu rẹ si ndun, ni obinrin na ba ju ibora aṣọ adirẹ kan si, were ni o ti gba, ti o si ti fi lọ idi, ni awọn mejeji ba jijọ yilu bẹdi, ki nma fa ọrọ gun lọ titi bayi ni Nini-owo ati iranṣẹ binrin Ọba yi fi jijọ sun pọ mọju.

ILẸ MỌ, ỌBA R E T I WỌN, KO RI WỌN

Nigbati ilẹ mọ ti orun fẹrẹ kan atari, ni Ọba pe awọn iranṣẹ rẹ obinrin yoku, o ni ẹ gbọ na alejo wa to wọlu lana, ti mo ni ki ọkan ninu yin lọ fi wọ si ile rẹ, nko ri alejo na? bẹni nko si ri arabinrin na, ẹ jọwọ ẹ ba mi pe Ikọ mi ki o wa wọn lọ. Kiamọsa Ikọ ti gberaṣọ o di ile iransẹ-binrin na nigbati o de ibẹ o kanlẹkun titi, ko gbọ ijẹ, ni o ba gba o j u ferese wọle, o kan ba wọn ti wọn nsọwọ kan toku lowurọ ni Ha! ṣe Ikọ Ọba, o ni iru iṣẹ kini a jẹ fọba bayi, o ni iwọ obinrin yi, o ti mọ wipe ẹniti o ba dan iru eyi wo pipa ni awọn mejeji, nko si fẹ ki o jẹ wipe emi ni ngo sọ fun Ọba pe ẹ hu iru iwa ti o lodi si ofin yi.

NINI—OWO NWO KORAN

Nini-owo n w o kọran, ko tilẹ sọrọ rara, ni Ikọ Ọba ba bere lọwọ rẹ pe o ko tilẹ ri ohun ti o le sọ si ọrọ yi, ọtọ ni ohun ti o le ẹ wọlu ẹtọ ni ohun ti e wa nṣe. nkan ti oju mi ri ni ngo ro fun Ọba o, ẹnyin lẹ mọ bi ẹ o ti ṣe yọ ara yin o, nigbayi ni Nini-owo wa bẹrẹ si gbọn riri. Ki wọn to tẹle Ikọ Ọba, iranṣẹ binrin na pe Nini-owo si kọrọ, o ni ko ma ṣe bẹru, on yio yọ ninu ọran na, o ni ti Ọba ba sa ti bere ọrọ lọwọ rẹ ki o ma ṣe bi asinwin, ki o si ma gbọ ohun ti on yio ma sọ.

IKỌ ỌBA ṢAJU WỌN DELE

Ikọ Ọba ṣaju wọn dele, nigbati wọn de iwaju Ọba gbogbo wọn yilẹ, Ikọ ni k a b i y e s i alaiyeluwa, mo ko wọn de o, ati pe awọn mejeji ti lodi si ofin ilu wa nipa biba ara wọn lopọ, Ọba binrin ... ni agbẹdọ, o ni ti o ba ṣẹ bẹ ni ki wọn lọ ti Nini-owo m ọ t e fun oṣu kan gbako ki wọn ma si jẹki iranṣẹ binrin on yiṣẹ ninu ọgba yi nigbati oṣu kan pe, oṣun han lera iranṣẹ bi ... na.

---

## Obinrin ti o koko ...wo ise Ijoba ile Rhodesia



Obinrin ti'a nwo yi ni Omidan Mavis Gumede ọmọ ọdun mejilelogun ara ilẹ Bulawayo ni Ipinlẹ Rhodesia ni Ijọba ilẹ Rhodesia ti o mbẹ nilu L o n d o n kọkọ gba sibi iṣẹ wọn ninu Ẹya Obinrin.

---

## Baba Egbe ile Sinegal ndagbere



Nigbati Ọgbẹni Leopold Senghor tiṣe Baba ẹgbẹ ilẹ Senegal mbọ lati ilu awọn Faranse o ya nilu Gẹsi, on ... a ni ... nwo ninu aworan yi ti Ọgbẹni Lord Home tiṣe Akọwe Gẹsi fun ilẹ okere ndagbere fun nigbati o fẹ wọ ọkọ ofurufu nilu Londonu ninu abẹwo ọjọ marun rẹ si ilẹ Gẹsi.

# Ninu ohun gbogbo, e tete ko ma wa Ijoba Olorun na

Lati Ọwọ:- LATIFU BABALỌLA
Akọwe Agba Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

MO KI GBOGBO ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ paapa Ẹnyin Musulumi ododo ẹ ku o ngbẹ yi o, Ọlọrun yio jẹki ẹmi o şika rẹ o, Oluwa koni fi arẹ şe wa o.

Iwọ ọrẹ mi ti o nka iwe Irohin Imọlẹ yi ni mo mba wi, ẹ tete ma wa Ijọba Ọlọrun na, o dara, o si tilẹ suwọn ki a sin Ọlọrun lati igba ewe titi digba ogbo, ẹ ma wa Ọlọrun nigbati ẹ le ri, ki ẹ si pe nigbati o bẹ nitosi.

Ninu ile Aiye li enia tile şe abamọ, şugbọn abamọ kosi ni Ajirọn, enia iba fi gbogbo ọjọ aiye rẹ sọrọ rere, ki o fi huwa rere, ki o si sin Ọlọrun lọsan ati loru, şugbọn ẹniti ko hu iwa buruku ri ti o si jẹ wipe li akoko ti o ya lati lọ jẹ ipe Ẹlẹda rẹ, ni Iku ka işẹ buruku na mọ lọwọ, nşe ni a o gbagbe gbogbo işẹ rere ti o ti nşe sẹhin yio si bọ sinu Iya ailopin.

Nikẹhin ọjọ onişe rere yio şe abamọ, bakanna ni onişe buruku yio şe abamọ, Nigbati awọn tonhuwa buruku ba njaye wọn lọwọ, nigbana ni nwọn o ma ke pe abamọ wipe Ye! Ye!! Oroo, mba mo wipe bayi bayi ni igbẹhin na yio ri mba ti kọ iwa buruku silẹ

Awọn onişe rere ẹwẹ, yio ma ke abamọ wipe Ha! Ọlọrun o, ibaşe wipe a mọ pe bayi ni işẹ rere dun to gbogbo ọjọ aiye wa ni a ba fi sisẹ rere, nitorina o di ọwọ gbogbo wa o.

Nitorina mo pe ẹnyin Musulumi ati Onigbagbọ ododo ẹ jẹki a ma sin Oluwa wa ẹ jẹki a fi işẹ buruku ati işẹ okunkun silẹ, ki a si ma fi gbogbo ọjo aiye wa se rere nitori a ko mọ asiko ti Ọlọjọ yio de, nitori ti o ba de ko le ba işẹ rere lọwọ wa. Ẹ maşe gbin Igi Oro nitori ẹhin - Ọla Ẹ jẹki a ma wa Oluwa nigbati a le ri ki a si ma pe nigbati o wa nitosi Ibẹru Oluwa ni ipinlẹsẹ ọgbọn ẹ jẹki a bẹru Ọlọrun Ẹlẹda wa.


## MOGBAYI COUGH MIXTURE

Mogbayi Cough Mixture jẹ Ogun Ikọ pataki ti a şe ni aşepe lati wo awọn Ikọ orişirişi san ni kiakia. O dara fun Ikọ agbalagba ati Ikọ ọmọde bẹni o si tun dara fun Ikọ ọmọ ọwọ pẹlu.

O dara pupọ ju gbogbo ogun Ikọ yoku lọ. O dara fun awọn arun Ikọ wọnyi, Ikọ ti o ma nha enia ni ohun, Ikọ ti o ma npọn enia loju, Ikọ ti ki jẹ ki enia sun dada, Ikọ ti o ma ndun enia lẹgbẹ, Ikọ ti o ma nta enia ni aya, Ikọ ti o ma nfa Ẹfọri, Ikọ ti o ma nfa arẹ ba ara, Ikọ ti o nmu ki enia ma pọ ẹjẹ, ati awọn Aisan miran ti wọn somọ Ikọ bi aiperi, oyi etc.

Mogbayi Cough Mixture yi dara pupọ fun ẹnyin ti Ikọ nyọ lẹnu. Ẹ ma şe şahun fun alafia ara yin, alafia ni opin ọrọ ijafara ni ewu pupọ, tete lọ ra Igo kan. Mogbayi Cough Mixture, yio wa ni ile itaja Egbogi ti o wa ni adugbo rẹ, Igo kan rẹ jẹ 2/6d arapọ rẹ jẹ 24/-.)




LILO RẸ:-

Ọmọ oşu mẹta — Idaji şibi tii kan ni wakati mẹtamẹta
Ọmọ oşu mẹta si mejila - Şibi tii kan nigba mẹta lojojumọ
Ọmọ ọdun kan si mẹfa.- Şibi tii meji nigba mẹta lojumọ
Agbalagba ———— Şibi Imukọ kan nigba mẹta lojumọ

*Wholesale Distributors:-*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHER

6,Balogun treet West
Lagos Nigeria.
Phone 22515.

34, Docemu Street,
Lagos.
Phone 24247.


# Oro nipa Awe awọn Imale ati Igbagbo

Lati Ọwọ:- WOLI KOGBEREGBE.

Mo ki yin ẹku ọdun awẹ yi, ọpọ enia lo npa irọ tan ara rẹ jẹ, to nsọ wipe on ngba awẹ, Ti enia kan ba gba awẹ, ko yẹ lati ma kanra, ọpọ enia lo ma wipe ẹku o ngbẹ o, Ọlọrun ko fi ongbẹ gbẹ ẹnikan rara o, ọpọ ẹlomiran lo nlọ ji ẹdiẹ gbe ni adugbo, Iru awọn enia bẹ lo mba awọn Imale Ododo jẹ.

Ha! Gbogbo ẹnyin Alaji ati ẹnyin Lemamu, ẹ lọ kilọ fun awọn enia ti ma wipe ẹku ongbẹ awẹ rẹ di melo? Ọpọlọpọ enia lo ngba awe, ti gbogbo onjẹ adugbo ko to jẹ Ha! asiwere pọ ni ile Aiye yi, Bi ọpọlọpọ ba ti gba awẹ tan, ko tun de Mọsalasi mọ, fẹ ki ẹ mọ wipe Imale mọ yin mọyin ati akara lo pọju ni ile aiye yi, ọpọlọpọ ni yio ma fi ebi pa ara rẹ, ti yio si ma fi ori balẹ fun ofo. Gbogbo ẹnyin Alhaji ati gbogbo ẹnyin Lemamu enia melo ni ẹ ri ni Mọsalasi nigbati awẹ ko ti de? Ọpọlọpọ yio tori ki nwọn bale mọ pe ongbawẹ lose kirun awẹ rẹ di ọgọrun, Loju gbogbo awọn Obinrin ni nwọn o si ma kigbe wipe Ha! ye! awẹ yi gbo mi loni Ẹnyin nwa iyin enia ẹnyin ko wa iyin Ọlọrun rara, ẹnyin fẹ Iyin enia ju Iyin Ọlọrun lọ JOHANU 12 Ẹ S Ẹ 43.


WOLI KOGBEREGBE

Moni lati sọ fun yin loni, Ẹ mase tan ara yin jẹ rara, bi iwọ ba mo pe iwọ kole şe ko ma kigbe wipe awẹ yi ma gbo mi, ongbẹ yi ma pọju o, Ma wulẹ gbawẹ rara, ki tirẹ ma jẹ si Iya ainipẹkun. Ati pẹlu nigbati ẹnyin ba ngba awẹ ẹ mase dabi awọn agabagebe ti nfajuro, nwọn a si ba oju jẹ, ki nwọn na le fi ara han fun enia pe wọn gbawẹ, Lotọ ni mo wi fun yin nwọn ti gba ere wọn na, şugbọn nigbati iwọ ba ngbawẹ fi ororo kun oju rẹ, ki o si bo oju rẹ pẹlu, ki iwọ ki o mase fi ara han fun enia pe iwọ gbawẹ, Bi kose fun Baba rẹ ti mbẹ ni ọrun.

Ọlọrun to ri ọ ni ikọkọ wipe iwọ ngba awẹ, yio si san fun ọ ni gbangba MATTEU 6, ẸSẸ 16, Ẹnikẹni to ba fẹ lati ma se aşe han yio jogun itiju ainipẹkun, Ha! Ile aiye yi şoro finu han o jẹ lọ şọra rẹ, gbogbo enia lo deke aiye daiye agunla, işẹ ni baba wahala. Adura temi nipe ki Ọlọrun dakun ko ma kẹhin si mi niteri Igbẹkẹle enia asan ni.

Ẹnyin yio ma gbọ ọrọ mi Iyokun ni ọsẹ to mbọ wa, Oluwa yio pẹlu gbogbo wa o.


## Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi ailowolọwọ ba nda ọ lamu, biairọmọbi mba ọ lọkan jẹ, tabi airişẹşe lo nyọọ lẹnu, tabi o tilẹ nşişẹ na owo işẹ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiye rẹ ni gbogbo ọna kona.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ẹjọ.

Mọ daju wipe diẹdiẹ lo kọkọ bẹrẹ. Ki o si tun ọna rẹ şe. Kọwe pẹlu Şile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni tọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunşe adanwo na lọdọ:-

AWORAWỌ
16, MỌLẸYE STREET
P. O. BOX 166 YABA - NIGERA

# Nje iru Igbeyawo bayi le yori si rere?

IBERE LỌDỌ IYAFIN ALAKẸ:-

Mo jẹ ọmọ ọdun merinlelogun mo si dagba pẹlu ọmọ obinrin ọmọ ọdun metalelogun (23 years) Iya ọmọ na ti nfẹ ki emi pẹlu ọmọ rẹ fẹ ara wa tipẹ emi si mọ pe Iya na nfẹ ki fẹ ọmọ binrin on, mo lero pe igbeyawo emi pẹlu ọmọ na yio yori si ire nitori pe ajijọ dagba ni ati pe a mọ ara wa daradara ṣugbọn emi ko ri daju pe ọmọdebinrin na ni ifẹ mi lọkan.

Bi o ba fẹ mi, yio jẹ pe iya rẹ lo jẹ ki o fẹ mi Njẹ iwọ Iyafin, ẹ lero pe iru Igbeyawọ ti o jẹ pe iya ọmọ lo fẹ ki a fẹ ọmọ on na yio yori si rere?

SHOMOLU — RASHIDI OLAWALE

IDAHUN:-

Emi ko lero pe enia le paṣẹ fun ifẹ, Bi o ba mọ daju pe ọmọbirin yi ko nifẹ rẹ lọkan, Amọran mi si ọ ni wipe ki o lọ sọ fun Iya rẹ pe ọmọ na ko ni fẹ si ọ, ofo ni yio jasi ti o ba gbiyanju lati tẹ Iya ọmọ na lọrun nipa ki o fẹ ọmọ rẹ ti o mọ pe ko ni fẹ rẹ lọkan.

ỌNA TO JIN PUPỌ LO NGBE

IBERE:- Mo jẹ ọmọ Ogun Ọdun, mo si nfẹ ọkunrin kan ọmọ ọdun mẹdọgbọn, laipẹ yi, emi kọwe si awọn Obi mi pe mo ti ri eniti emi yio fi ṣe ọkọ, wọn si da esi pada si mi pe nwọn ko fẹ ki fẹ ọkunrin na, ti mo ba si fẹ awọn ki yio ṣe Adura fun mi nitori pe ọkunrin na ngbe ọna jinjin si wa nwọn fẹ ya emi pẹlu ọkurin na, ṣugbọn Alakẹ, emi ni ifẹ ọkunrin yi pupọ.

Njẹ o lero pe yio buru ju fun mi bi mo ba ba ọkunrin na salọ laiko gba aṣẹ lẹnu awọn Obi mi?

OSHOGBO, — ADIYAT SARIU

IDAHUN:- o jẹ enu fun awọn obi rẹ nipa atako Igbeyawo rẹ, ṣugbọn iwọ ko mọ wipe iwọ si le yi ọrọ ti nwọn yi pada, ki lo ṣe ti o ko fi gba ọkọ rẹ yi ni amọran lati wa si ọdọ awọn obi rẹ ki o wa pari rẹ.

Awọn obi a ma kọ lati ma fi ọmọ wọn fun eniti wọn ko ba mọ nkankan nipa ile ati ọna rẹ, A ko si le ba won wi nipa ọrọ yi, Nisisiyi, ki o to ṣe nkan kan to yanju, sọ fun ọkọ rẹ pe ko wa ba awọn obi rẹ sọrọ, mo mọ daju pe gbogbo rẹ ko ti kọja ju.

AKIYESI:- Ẹ tun bọ ma fi awọn ibere ẹdun ọkan yin nipa ifẹ ranṣẹ si IYAFIN ALAKẸ c/o OLOTU IROHIN IMỌLẸ, 16, BAMGBOSE STREET LAGOS.

---

IBITI A NI KI GBEGBE MA GBE IBẸ NI GBE

# Kenyata se be o di Baba

Ẹniti a nwo yi ni Jọmọ Kẹnyata ọmọ Ilu Kenya Ilewe awọn ara Scotland lo gbe kọwe lọdun 1920, awọn ọmọ Kẹnya da Ẹgbẹ kan silẹ ti nwọn npe ni K. C. A. Jọmọ yi ni akọwe ẹgbẹ na.

Lọdun 1931, o lọ silu Oyinbo, ọdun mẹrindinlogun lo gbe lọhun, O kọwe ni Quaker College, lẹhin na ni London University bi o ti kuro ni bẹ, iṣẹ Olukọ lo bẹrẹ o gba oye Economic ti London lọdun 1936 Jọmọ da Ẹgbẹ kan silẹ ni Ilu Oyinbo lọdun 1945, o si pada silu rẹ ni ọdun 1946, Ijọba ki mọlẹ ni ọdun 1952 nwọn ni o lọwọ ninu ẹgbẹ Awo Mau-mau Nitori eyi, nwọn ju si ẹwọn fun ọdun mẹfa nwọn si da silẹ ni ọdun 1959 ṣugbọn o loju ibiti o gbọdọ de.



Nwọn da silẹ patapata ni ọdun 1961, o si pada lọ sile, o si di Baba Ẹgbẹ K. A. N. U.

---

## Awon egbe Onisegun Kingsway fe da Egbe titun kan sile

EKO:- Irohin kan wa wipe awọn Onisowo Kingsway Chemist ti ilẹ Naijiria ngbero lati parapọ di ọkan, nigbati nwọn ba pari eto na tan, awọn ti yio jẹ alabojuto rẹ niwọnyi:-

1. Ọgbẹni G. W. Griffiths (2) Ọgbẹni J. B. Davies O. B. E., (3) Ọgbẹni J. O. Paul, (4) Ọgbẹni C. V. Efobi 5. Ọgbẹni R. V. Obi, (6) H. Godwin Brown, (7) J. M. Garsten.

Kingsway Chemist ni orukọ ẹgbẹ na yio ma jẹ nigbati o ba bẹrẹ, o si jẹ ẹka kan lara iṣẹ owo U. A. C.

Awon enia meji ti nwọn tun gbe si ipo giga ni Ọgbẹni A. O. Ọlọrunfẹ Ojo ati J. A. Ogundipẹ ti nwọn gbega si ipo Accountant Ọlọrunfẹ Ojo di Alabojuto U. A. C. nibi gboggbo.

---


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI A NPE NI:-

## "UROXAL"



Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney-Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ẹhin didun eri ile tabi itọ-jijo enia, itọ riru, rukuruku Pipọn tabi riruo, lakuregbe, Ibara di wiwo, orunkun, owọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju, aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia, didaji loru nigbakugba, ati oriṣiriṣi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara re ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni Ilu Naijiria nitorina ṣọra ki awọn eleru tabi awọn Oni rọbirọbi ma ta oriṣi omiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba a rara o! Owo rẹ jẹ Ṣile Mẹfa abọ 6/6d owo ọkọ ṣile meji abọ (2/ 6d)

Bere Egbogi yi ni Ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

**OLOYE AWOLOWO SO PE:-**

## NAIJIRIA YIO DI ONIGBESE TI IJOBA KO BA DAWO INAKUNA DURO

Ni Ipade nla ti ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ se ni Jos ni ilẹ Hausa Oloye Awolọwọ, Baba ẹgbẹ, fihan pe ti Ijọba apapọ ko ba da ọwọ duro ninu inakuna, ki nwọn si ro bi owo yio ṣe ma wọle, Naijiria yio wọ gbese nla.

Oloye Awolọwọ ni gbese ti o ti wa nilẹ ti pọ to ko si yọ ki a tun fi kun.

O ni ọpọlọpọ igba ni on ti kigbe ni ile Aṣofin ni Eko gẹgẹbi Olori alatako pe inakuna pọ, ṣugbọn nwọn ko ka ọrọ on si.

O ni inu on dun ṣa, on si ba awọn ọmọ ẹgbẹ on yọ pe gẹgẹbi iṣẹ wọn, Ijọba Iwọ Orun nibiti ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nṣe Ijọba, ti fi apẹrẹ lelẹ. Nwọn ti ge owo Oṣelu ati ti oṣiṣẹ Ijọba ti o ngba owo nlanla ku.

Eyi yio fa owo wọle fun Ijọba Iwọ Orun, ṣugbọn sibẹsibẹ ni iwọn igbati owo ti a nwa lati fi ṣe Ilọsiwaju si ilu pọ, gbogbo enia ti o ku yatọ si Oṣelu ni lati mura ati sa Ipa t i n u tinu nigbati Ijọba ba ke si wọn.

Oloye A w o l ọ w ọ ni ti I j ọ b a ti apapọ ba le din ọja rira lati okere ku papa awọn nkan ti a le ri nihin, ki o si ṣe Iranlọwọ fun Ijọba Ipinlẹ kọkan lati ma tọju Agbẹ ati iṣẹ oko, ki o si wa oriṣiriṣi ọna ti yio fi polowo ati ti yio fi ta awọn ọja wa si awọn ilu ti ko nba wa lọ nisisiyi ( Ilu bi A s i a, Japan ati India) Owo yio wọle fun ilẹ Naijiria.

Ti nwọn ba si le din inakuna ni ile gbese ko ni pọ mọ.

---

## Akapo Owo ile Tanganyika



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni Paul Bọmani on lo ti nṣe Aṣoju fun Ilọsiwaju ẹgbẹ fun ilẹ Tangayiaka ki o to wa dipe o gba ipo Akapo lọwọ oyinbo ti o mbẹ tẹlẹ ki ilu wọn to gba Ominira lọdun tokọja.

Nisisiyi Ọgbẹni Paul ti di Akapo owo ilẹ Tanganyika.

---

EYI NI IDAHUN AWỌN IBERE TO WA NI OJU EWE KẸTA

(1) Ọgbẹni Rashidi K a w a w a (2) Julius Nyerere
(3) Ọlọla Roy Welensky (4) Ọgbẹni Ofori Atta
(5) Ọgbẹni Ako (6) Lọdun 1900 (7) Lọdun 1912
(8) Mississipi (9) Jọmọ Kẹnyatta.
(10) Kehaweri ni ẹkun kikunyu

## Iwo ha Nfe Igbega bi?

Fun anfani awọn ti o ngbe Eko, ti ko le mọ ile Iṣẹ wa ni Mushin, ni a ṣe ko awọn apakan ninu ọja wa, wa si Nọmba 16, Bamgbose Street, Lagos, ẹnikẹni ti o ba fẹ ra ọja na wa ni Eko ki o ma lọ sibẹ.

TURARI AJẸBIDAN AGBABIETU

Turari yi ko ni ẹgbẹ akose fun awọn ajẹ ni, ti o ba loo iwọ ko ni mọ a i t a ọja. Adura rẹ yio si ma a gba Awọn enia buruku aiye kolẹ ni lagbara lori rẹ onṣiṣẹ to igba ọna (200 ways) fun igbega ọmọ enia ni le A i y e. (Pangolo 10/6d)

MANAGER (J. O. SHOYINKA.) c/o IROHIN IMỌLẸ 16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.

---

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TỌINKI TITUN TI O ṢEṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN ATI OBINRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dọkita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ de ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de ọkọn lọsan tabi loru tabi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara arẹE-emi (breath) inu rẹ ko ba gunle dara dara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣe ko "NJẸ" fun awọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọ d u n lọ si dede adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara lọjọ Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara re ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kọnkọn nigba kugba "Arẹ" nigbakubga yio salọ patapata Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:

NIGERIN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OṢHOGBO

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# FEDERATION OF NIGERIA THIRD DEVELOPMENT LOAN

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £7 million registered Stock in Februray/March, 1962. The Stocks to be issued will be:-

1. £2 million 5% Federation of Nigeria Third Development Stock 1966 - to be repaid in full on 7th June, 1966.
2. £5 million 6% Federation of Nigeria Third Development Stock 1986 - to be repaid in full on 7th June, 1986.

Both Stocks will be issued in multiples of £10 at par, and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the Central Bank during the period 26th February to 26th March 1962.

Prospectuses, which contain full information, and application forms may be obtained from banks or at the Central Bank on or after 26th February, 1962.

*W. A. TIBBLES.*
*General Manager.*

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
FEBRUARY, 1962.



BERE OJULOWO EGBOGI WONYI:-

## "Congreve Female Remedy"

Egbogi pataki fun Itoju tabi Ajo Obinrin fun Inu ririn Ehin, Ibadi riro tabi gige nigbakugba Ęsanri, ara tabi Inu Gbigbona, Ęję dudu, ati orișirișí arun tabi amọdi ti o ma nyọ Obinrin lẹnu ni Inu nigbakugba.

## "Collomack"

Egbogi awọn Jamani ti o dara julọ fun Itanpara, awọ ESE lile, Igbado ẹsẹ ti ki jẹki enia le wọ bata (Corncure) ati orișirișí arun Ęsẹ miran pẹlu ni.

## "Mackctal"

Atamatase Egbogi awọn Jamani fun orișirișí amodi ETI" riro tabi didun fun ọmọde ati agbalagba bi o ti wun ki ọjọ rẹ ti pẹ to yio șe iwosan rẹ ni kiakia.

## "Medupríval"

Ojulowo egbogi awọn ara ilu Tatanbulu fun iwosan ni kiakia gbogbo amodi tabi OTUTU Agbari, Igba aiya Ọna-ọfun, Imu tutu tabi ti o ma nsomi bi ikun nigbakugba, Kẹlẹbẹ ọna ọfun tabi agbari hiha, amurun ati orișirișí amodi miran gbogbo ti ibẹrẹ rẹ jẹ otutu. Bere ti Ọmọde tabi ti agbalagba wọn yato nipa agbara wọn ni o

Bere ni Sọbu:—
**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.


## Ijoba fe tun Hosibitulu Ilu Eko ko

Ọgbẹni Lawson ẹniti nșe Olori oșișẹ ile Iwosan ni Eko sọ ni ipade ti o pe pẹlu awọn oni iwe irohin pe Ijọba ṣetan lati tun ile Iwosan ti Ọdan ni Eko kọ.

O ni Ijọba ngbiyanju lati gba Dokita sii, eyi si pẹlu ohun ti o mu Ọiala Majẹkodunmi, Olotu Ijọba ni ibi iṣẹ iwosan lọ si ilu Ọba. Ọgbẹni Lawson ni nigbati iṣẹ atunse na ba pari, Ile iwosan na yio ni aye fun ọgọrun mẹje ibusun yio si ni ile fun awọn Dokita ati oșișẹ.

## Odidi Ilu gba Ina ni Abakaliki

Ni ileto kan ti orukọ rẹ njẹ Umu Omeme Izza, ni Abakaliki ni a gbọ iro pe nwọn pa Obirin kan, wọn si ki ina si ilu. A gbọ wipe Ọlọpa ti da ọkunrin kan duro lati fun wọn ni Iranlọwọ lati wadi ẹniti o șe iṣẹ buruku na. Bi ina na si ti șe njo bẹ ni awọn ara ilu na nko ẹru wọn ti nwọn si nsa lọ sinu igbo.

## Reluwe da Osise won sile

EKO:- Irohin ta si wa leti wipe, gbogbo awọn oșișẹ Reluwe ti o ti di ogunna-gbogbo li ẹnu ṣẹ ọkọ ilẹ, yala onișẹ ọwọ tabi awọn akọwe ti nwọn ti di Orisa mọlẹ nibi iṣẹ na tabi awọn ti ọjọ ori wọn ti to ẹniti o le fẹhinti ki o si ma jẹ onjẹ Reluwe, gbogbo wọn pata-pata ni yio gba idaduro kuro lẹnu iṣẹ ni ipari oșu ti o mbọ.

A gbọ wipe apapọ gbogbo awọn ti nwọn yio da silẹ jẹ 4, 474 enia.

## Ebun Eko Ofe fun Omodebinrin

A gbọ Irohin wipe awọn Oyinbo Pan Electric Ltd fun Ọmọ oșișẹ wọn kan ni ẹbun ẹkọ Ọlọfẹ lati lọ kọ ẹkọ kun ẹkọ rẹ ni ile ẹkọ giga, Orukọ Ọmọbinrin ti o gba ẹbun ẹkọ Ọlọfẹ na a ma jẹ Joy. I. Odiachi, ọmọ ọdun mẹtala nise, o si jẹ ọmọ bibi nu Ọgbẹni Francis N. Odiachi tiṣe ọkan ninu awọn oșișẹ Oyinbo Pan Electric Limited. Ile Ękọ ti ọmọbinrin na yio gbe lọ kọ ẹkọ Ofẹ fun ọdun m a r u n ni ile ẹkọ giga ti awọn npe ni Queens's College ni Eko.


# DURO KO OGBON

(1) Ọla ni fun enia lati ș i w ọ kuro ninu ija șugbọn Olukuluku asiwere ni ima ja ija nla

(2) Ęniti nkọja lọ, ti o si dasi ija ti ki ise tirẹ, o dabi ẹniti o mu Aja leti.



AKIYESI FUN ENITI OFẸ RA TABI TA ILE TABI ILẸ NI IBI GBOGBO

Ęnikẹni ti o ba fẹ ra tabi tita tabi fifi ile ya, tabi lati haya le to dara ti o si laye tabi ile iṣẹ tabi ilẹ e y i t i ko pọju adọta ẹsẹ ni fifẹ ati ọgọrun ẹsẹ ni gigun, nibia tabi lọhun ati nibi gbogbo, bi Eko, Ebute mẹtta, Apapa Yaba Suru Lere, New Lagos, ati ni Idi Oro, M u ș h i n Isọlọ Rood ati Ikẹja tabi nibikibi, Wa ri Ọgbẹni:-

**J. B. Crowsson Edujobi & Sons**

1st floor 16, BAMGBOȘE STREET LAGOS

Tabi ki o pe wa lori ẹrọ Isọrọ No 24318.


Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985 Olotu E. A. Adeniji 24, Oliyide Street, Odu Abọrọ MUSHIN.